Pákò jẹ́ imọ́toto fun ẹnu, ó sì jẹ́ okunfa iyọnu Oluwa

Lati ọdọ Aisha - ki Ọlọhun yọnu si i - ó sọ pé: Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pé: "Pákò jẹ́ imọ́toto fun ẹnu, ó sì jẹ́ okunfa iyọnu Oluwa".

[O ni alaafia] [Nasaa'iy ati Ahmad ni wọ́n gba a wa]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - n sọ fún wa pé ìmáa ṣe imọ́toto eyín pẹlu igi araak (pákò) tabi iru rẹ̀, ó máa n fọ ẹnu mọ́ tonitoni kuro nibi awọn idọ́ti ati oorun tí kò dara ni, ati pé ó jẹ́ ọkan ninu awọn okunfa iyọnu Ọlọhun si ẹru Rẹ̀; nítorí pé ó jẹ́ ìtẹ́lé ti Ọlọ́hun àti ìdáhùn sí àṣẹ Rẹ̀, ati nítorí pé ìmọ́tótó tí Ọlọ́hun Ọba nífẹ́ẹ́ sí wà ninu rẹ̀.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3588